# Gbogbo Ohun Tí Ó Yẹ Láti Mọ́ Nípa Àrùn Coronavirus(COVID-19)



## Ìwé ìléwọ́ fún Àwọn Ọmọdé

LÓRÍ

# ÀRÙN CORONA [COVID-19]




NCDC
NIGERIA CENTRE FOR DISEASE CONTROL
FEDERAL MINISTRY OF HEALTH

**Yoruba**

unicef
for every child

# Àkóónú




Kí ni Coronavirus tàbí COVID-19? 1

Báwo ni àwọn ènìyàn ṣe lè ní tàbí kó kòkòrò àrùn COVID-19? 2

Ta-a-ni ó lè kó àrùn COVID-19? 3

Báwo ni mo ṣe lè dáàbòbo ara mi láti má kò ó àrùn COVID-19? 4

- Báwo ni o ṣe lè dáàbòbò ara rẹ tí o bá ń fọ ọwọ́ rẹ? 7
- Ní ìgbà wo ni mo lè fọ ọwọ́ mi? 8

Má ṣe gba irọ́ tàbí ọ̀rọ̀ àhesọ gbó nípa COVID-19! 9

Bí àwọn òbí ṣe lè lọ́wọ́ sí ẹ̀kọ́ kíkọ́ àwọn ọmọ ní ilé 12

# Kí ni Coronavirus tàbí COVID-19





Coronavirus jẹ́ àrùn tí ó burú púpọ̀ tí ó ń kóbá ẹ̀yà ara tí a fi ń mí àti ọ̀nà ọ̀fun. À ń pè é ní COVID-19 torí wí pé 'CO' dúró fún Corona, 'VI' dúró fún Virus, 'D' dúró fún Disease, nígbà tí 19 dúrófún 2019.



Nígbà tí ẹnìkan bá ní àrùn COVID-19, wọn á bẹ̀rẹ̀ sí í wúkọ́, pẹ̀lú ibà bẹ́ẹ̀ni wọn kò ní í le è mí dáadáa.

Kò tíì sí òògùn kankan fún COVID-19. Ṣùgbọ́n àwọn tí ó ní àrùn yìí lè rí ìwòsàn tí wọ́n bá tètè rí ìtọ́jú ní kíákíá ní ilé-ìwòsàn pẹ̀lú ìtọ́jú tó péye láti ọwọ́ àwọn dókítà àti nọ́ọ̀sì. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tí ara wọn kò yá láti ipaṣẹ̀COVID-19 ni wọ́n ti gbádùn báyìí torí pé wọ́n tètè rí ìtọ́jú tó péye.





Tí àwọn ènìyàn tó ní àrùn COVID-19 kò bá tètè rí ìtọ́jú tí àrùn yìí fi wọ̀ wọ́n lára, àrùn yìí lè dá wọn gúnlẹ̀, wọ́n sì le kú láti ibẹ̀.



# Bá wo ni àwọn ènìyàn ṣe lè kó covid-19?

Àwọn ènìyàn ń kó àrùn COVID-19 nípaṣẹ̀ àwọn ọ̀nà yìí:



Nígbà tí o bá mí èémí tí ó ní omi tín-tìn-tín tí ó fọn j
áde láti imú ẹni tí ó ní àrùn yìí nígbà tí ó bá sín.



Nígbà tí o bá mí èémí tí ó ní omi tín-tìn-tín tí ó fọn
jáde láti ẹnu ẹni tí ó ní àrùn yìí nígbà tí ó bá wúkọ́.



Nígbà tí o bá fi ọwọ́ kan ẹni tí ara rẹ̀ kò yá nípaṣẹ̀ COVID-19, tàbí tí
o bá fi ọwọ́ kan nǹkan tí àwọn alárùn yìí bá fi ọwọ́ kàn,
tí o wá fi ọwọ́ náà kan ojú rẹ.

Tí o kò bá ṣe ọ̀kankan nínú àwọn nǹkan wònyí,
a jẹ́ pé o kò le è ní COVID-19.

# Ta-a-ni ó lè ní COVID-19?



Ẹnikẹ́ni ni ó lè kó COVID-19, ṣùgbọ́n ó má a ń dààmú àwọn ìṣòrí àwọn ènìyàn wọ̀nyí púpọ̀:



Àwọn àgbàlagbà tàbí arúgbó



Àwọn tó ní àìsàn mìíràn lára bí i àrùn ìtò ṣúgà, àìsàn ọkàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.



Àwọn ọmọdé tí wọ́n bá wà ní àyíká àwọn tó ní àrùn yìí lè kó àrùn náà, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì le ní àwọn ìfarahàn/àmì tó gbópọn.

Ó ṣe pàtàkì kí á dáàbòbò bo gbogbo àwọn ọmọdé, àwọn àkàndá ènìyàn, aláboyún, àwọn tó wà ní ibùdó pàjáwìrì àti àwọn àlejò, aláìní àti àwọn tó kù díẹ̀ káà tó fún láwùjọ lọ́wọ́ àjàkálẹ̀ àrùn COVID-19.



# Bá Wo Ni Mo Ṣe Lè Dáàbò Bo Ara Mi Lọ́wọ́ Àrùn Covid-19

## Àwọn nǹkan tó jáfáfá díẹ̀ tí o lè ṣe kí o má baà kó àrùn COVID-19...



Má a fọ ọwọ́ rẹ ní ìgbà gbogbo pẹ̀lú ọ̀ṣẹ àti omi tó ń dà geere fún ogún ìṣẹ́jú-àáyá ó kéré tán.



Má ṣe bọ ẹnikẹ́ni lọ́wọ́



Má a bo ẹnu àti imú rẹ pẹ̀lú ìgbùnwó rẹ tàbí tíṣu-pepà nígbà tí o bá wúkọ́ tàbí tí o bá sín. Kí o sì ju tísú-pepà tí o bá lò sínú garawa ìdọ̀tí tó ní ìdérí kí o sì dé e lẹ́ṣẹ̀kẹṣẹ̀.



Má a fi òògùn olómi apakòkòrò tí a mọ̀ sí sanitáísà tó ní ògógóró nínú pa ọwọ́ rẹ ní ìgbà gbogbo.



Má ṣe má a fi ọwọ́ pa ojú, bẹ́ẹ̀ni kí o má ṣe má a ki ọwọ́ sí imú tàbí ojú rẹ





Tí o bá lọ sí ibi tí àrùn COVID-19 wà, tàbí tí o pàdé ẹni tí ó ní àrùn COVID-19, o ní láti rí i dájú pé o ya ara rẹ sọ́tọ̀ fún ọ̀sẹ̀ méjì kí o má baà kó àrùn yìí ran ẹlòmíràn

## Lásìkò ìyara-ẹni-sọ́tọ̀:



Wà ní yàrá ìyara-ẹni-sọ́tọ̀ tó ní fèrèsé fún ọjọ́ mẹ́rìnlá.



Tí o bá sàkíyèsí àmì tàbí àpẹẹrẹ kankan bíi ikọ́, ibà, tàbí wàhálà nípa èémí mímí, yára pe àwọn aláṣe ètò ìlera láti wá gbé ọ fún ìtọ́jú.



Nígbà tí o bá wà ní ìfarapamọ́/ìyara-ẹni-sọ́tọ̀, má ṣe jẹ́ kí ọkàn rẹ dààmú tàbí kí ó bẹ̀rù/jáyà. Gbìyànjú láti wá nǹkan ṣe bíi ìwé kíkà, ìtàn kíkọ, orin kíkọ, ṣe eré ìdárayá, tàbí àwọn nǹkan mìíràn.



Nínu ara àwọn nǹkan tí ọwọ́ ti kàn



Dúró sí ilé nígbà tí ara rẹ kò bá yá.



Ta kétésí ibi tí àwọn èniyàn bá pọ̀ sí.



Ríi dájú pé o fi ààyè bí i ìwọ̀n ẹsẹ bí i mẹ́wàá sílẹ̀ sí ààrin ìwọ àti àwọn èniyàn pẹ̀lú ẹni tó ní àrùn yìí.



Tí o bá ní àìsàn ibà, ikọ́, tàbí ìsòro láti mí dáadáa, tètè sọ fún àwọn òbí rẹ tàbí alágbàtọ́ rẹ kí wọ́n ba à le tètè ṣètò ìtọ́jú tó yẹ fún ọ.

# Bí a ṣe Lè Fọ Ọwọ́dáadáa






Fọ́n omi tíó ń dà geere sí ọwọ́ rẹ




Fi ọṣẹ tí ó tó sí ọwọ́ rẹ tí o ti fi omi wọ́n.




Gbo àtẹ́lẹwọ́ rẹ dáadáa títí kan ẹ̀yìn ọwọ́ rẹ, ọrùn ọwọ́ rẹ, ààrin ìka rẹ, àti abẹ́ èék-ánná rẹ fún ogún ìṣẹ́jú-ààyá ó kéré tán.




Fi okàn sí àwọn àtànpàròkò rẹ.




Tẹ orí ìka rẹ sínú àtẹ́lẹwọ́ rẹ kọ̀ọ̀kan.




Ṣan ọwọ́ rẹ dáadáa pẹ̀lú omi tí ó ń dà geere.




Fi aṣọ tí ó mọ́ tónítóní nu ọwọ́ rẹ, tàbí kí o fi sílẹ̀ sí atẹ́gùn.

Ọ̀nà tí ó rọrùn láti lè ríi dájú pé a lo iye àkókò tó yẹni nípa kíkọ orin 'Happy birthday' ní èèmejì tàbi orin 'ABCDEFG'

# Ní gbà wo ni mo lè fọ ọwọ́ mi?



Fun gbogbo igba tàbí fún ti ìdènà àrùn COVID-19, o gbọ́dọ̀ má a fọ ọwọ́ rẹ ní àwọn ìgbà wọ̀nyí:

- Lẹ́yìn tí o bá ti fọn imú rẹ, wúkọ́, tàbí sín
- Lẹ́yìn tí o bá ṣe àbẹ̀wò sí àwọn ibùdó ní ìta gbangba bíi ibùdókọ̀, ọjà tàbí àwọn ibi ìjọsìn.
- Lẹ́yìn tí o bá ti fi ọwọ́ kan àwọn nǹkan ní ìta tí o bá jáde kúrò ní ilé rẹ tàbí tí o bá fi ọwọ́ kan owó
- Síwájú tàbí lẹ́yìn oúnjẹ
- Lẹ́yìn tí o bá lo ilé ìtọ̀ tàbí ilé ìyàgbẹ́
- Lẹ́yìn tí obá fi ọwọ́ kan ìdọ̀tí
- Síwájú, lásìkò àti lẹ́yìn tí o bá ti ṣe ìtọ́jú aláìsàn.
- Lẹ́yìn tí o bá fi ọwọ́ kan ẹranko àti nǹkan ọ̀sìn
- Lẹ́yìn tí o bá pààrọ̀ ìlédìí ọmọdé tàbí tí ò ń ran ọmọ lọ́wọ́ láti lo ilé ìyàgbẹ́



- Nígbà tí ó bá hàn gbangba pé ọwọ́ rẹ dọ̀tí

# Má Ṣe Gba Irọ́ Tàbí Àwọn Ọ̀rọ̀ Àhesọ Nípa COVID-19 Gbọ́





Má ṣe lo òògùn chloroquine tàbí ra àwọn òògùn mìíràn láti ṣe ìtọ́jú COVID-19. Gba àwọn onímọ̀ nípa ètò ìlera láàyè láti sọ fún ọ àwọn nǹkan tí o ní láti lò.




Àwọn ènìyàn kò gbọdọ̀ mu ògógóró láti dènà àrùn COVID-19.



Kí ẹ̀fọn jẹ ènìyàn kò le ṣe ìtànká àrùn COVID-19



Kí ènìyàn fi omi gbígbóná wẹ̀ kò dènà àrun COVID-19



Má ṣe yẹra tàbí sá fún àwọn tí ó ní àrùn yìí



Nígbà tí o bá ń ṣe àìsàn, o lè gbàdúrà. Ṣùgbọ́n o ní láti pe àwọn aláṣẹ ètò ìlera láti bèrè fún àyẹ̀wò kí wọ́n lè tọ̀jú rẹ bí ó ti yẹ, kí o sì le gba ìtọ́jú tó péye láti ọ̀dọ̀ àwọn dókítà àti àwọn nọ́ọ̀sì.



COVID-19 kì í ṣe àìsàn tóń ran olówó nìkan.










Tí o bá ní àìsàn ibà, ikó tàbí ìṣòro ní mímí, tètè sọ fún àwọn òbí tàbí alágbàtọ́ rẹ kí wọ́n ba à le tètè ṣètò ìtọ́jú tó yẹ fún ọ. Tí o bá rí ẹ̀rọ ìbára-ẹni-sòrò nítòsí, tètè pe nóḿbà NCDC yìí ní ọ̀fẹ́ 080097000010.



# Bí Àwọn Òbí Ṣe Lè Lọ́wọ́ Sí Ẹ̀kọ́ Kíkọ́ Àwọn Ọmọ Ní Ilé

## Gẹ́gẹ́ bí òbí, o lè túnbọ̀ lọ́wọ́ sí ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ nípa ṣíṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí:



Fi ìfẹ́ tíó yẹ hàn nípa ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ



Fi òfin lélẹ̀ kí o sì má a ṣe àmójútó tó yẹ nípa ìlo tẹlifíṣàn, eré ìdárayá orífídíò, àti ìlò ayélujára.



Ṣe ìlàsílẹ̀ ètò fún títẹ̀lé pẹ̀lú ọmọ rẹ. Fi iṣẹ́-ilé, ìwé kíkà, ìwé kíkọ, àwòrán yíyà, àti ìgbà eré ṣíṣe sí inúun rẹ̀. O lè fi ààyè sílẹ̀ fún àyípadà.



Bá ọmọ rẹ sọ̀rọ̀ –sàkíyèsí nǹkan tí wọ́n ń rò tàbí tí ó wà lọ́kàn wọ́n, kí o sì fi àkókò tí ó yẹ sílẹ̀ fún wọn.



Ti ọmọ rẹ lẹ́yìn láti tẹ̀lé àwọn ètò ẹ̀kọ́ pẹ̀lú ìtọ́ni rẹ. Èyí lè jẹ́ nípasẹ̀ ẹ̀rọ ayélujára, tẹlifíṣàn, rédíò, ìwé, tàbí kí o lo àwọn nǹkan kíkà tí a ṣe ní agbègbè wa.



Má ṣe jìnnà sí olùkọ́ ọmọ rẹ ní ilé-ìwé, tàbí àwọn òbí yòókù, àti àwọn ẹgbẹ́lẹ́gbẹ́ tó wà ní àwùjọ.



Kọ́ ọmọ rẹ ní àwọn iṣẹ́-ilé kọ̀ọ̀kan bíi iná dídá, nǹkan nínù, ilẹ̀ gbígbá, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.



# Ní Báyìí Tí O Ti Mọ Nǹkan Tí Àrùn Coronavirus Tàbí Covid-19 Jẹ́...

Ríi bí ojúṣe rẹ nípa sísọ fún àwọn ọ̀rẹ́ nípa rẹ̀, kí o sì rántí láti pa ara rẹ àti àwọn tí ó kù mọ́ láìléwu.






Láti mọ̀ síwájú síi nípa COVID-19 tàbí tí ìwọ tàbí ẹlòmíràn tí o mọ̀ bá ń fi àwọn àmì/àpẹẹrẹ COVID-19 hàn, jọ̀wọ́ pe nómbà tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.




Nọ́mbà ìpè ọ̀fẹ́ ti NCDC ni:

**08009700010**